IVADO

Initiative IA + Société / AI + Society

# Ṣíṣe ìjọba pẹ̀lú AI

## Àwọn ìgbésẹ̀ mẹ́rin láti mú àyípadà ọ̀tún àti ṣíṣe àkóso ìṣèjọba tó dúró ire

Catherine Régis, Florian Martin-Bariteau, Rachel Adams, Brunessen Bertrand, Jake Okechukwu Effoduh, Peter Parycek, Carlos Affonso Pereira de Souza, Hyesun (Melissa) Yoon

## Ìdide AI fún àwọn ètò ìjọba

Ìmọ̀ ẹ̀rọ ọgbọ́n àtinúdá, Artificial Intelligence (AI) ń lékún lójoojúmọ́ lórí bí ìjọba ṣe ń ṣètò, lórí bó ṣe ń nípa bí àwọn aráàlú ṣe ń fèsì sáwọn ètò ìjọba àti bí àwọn bí wọ́n ṣe ń ṣe ìlú. Lónìí, bíi ìdá àádọ́rin (70%) àwọn orílẹ̀ èdè káàkiri àgbáyé ni ìjábọ̀ sọ pé wọ́n ń lo AI láti fi mú ìgbòòrò bá àwọn ètò ìṣèjọba lábẹ́nú nígbà tí ìdá kan nínú ìdá mẹ́ta ń lò ó láti fi ṣe àtìlẹyìn gbígbé ètò kalẹ̀ àti ṣíṣẹ́ àmúṣẹ wọ́n.[1]

Bí àpẹẹrẹ, ìjọba àpapọ̀ Canada ṣàmúlò AI láti fi tú àwọn ìjábọ̀ tó lé ní 11,000 èyí tí àwọn aráàlú fi ránṣẹ́ lórí ṣíṣe àtúngbéyẹ̀wò àti ìlànà tí wọ́n ń gbà láti fi lo AI;[2] Singapore ti ṣí àwọn ìlànà ìbánisọ̀rọ̀ (chatbot) tó ń ṣàmúlò AI ní gbogbo ìkànnì tó jẹ́ ti ìjọba lójúnà àti ri dájú pé wọ́n ṣètò tó pojú owó;[3] bẹ́ẹ̀ náà ni ẹ̀ka tó ń rí sí ìpèsè omi ní Peru ń lo AI láti mọ iye omi tí orílẹ̀ èdè náà nílò.[4] Àwọn ìjọba kan ti gbáralé AI débi pé wọ́n ti ń wọ́nà láti máa lò ó fún àwọn ojúṣe ìjọba dípò lílò ó gẹ́gẹ́ bí irinṣẹ́ àtìlẹyìn lásán.[5]

Àwọn àǹfàní tí àfojúsùn wà láti jẹ látara AI le wá sí ìmúṣẹ tí ìjọba bá fi gbé àwọn ìlànà láti tẹ̀lé kalẹ̀, tí wọ́n sì gbé ìgbésẹ̀ láti ṣàmúṣẹ ìgbésẹ̀ AI pẹ̀lú pẹ̀lẹ́pẹ̀lẹ́ bí ìwádìí ṣe fi hàn pé "ìdá ọgọ́rin (80%) àwọn àkànṣe iṣẹ́ tí wọ́n fi AI ṣe ló ti rí ìjákulẹ̀ èyí tó jẹ́ àlékún ìdá méjì àwọn ìjákulẹ̀ àwọn èyí tí wọn kò fi AI ṣe."[6] Bí àpẹẹrẹ, ní Michigan, àwọn èèyàn tó fẹ́ẹ̀ tó 40,000 ni AI parọ́ ẹ̀sùn mọ́ pé wọ́n ń gba ẹ̀tọ́ àwọn tí kò nísẹ́,7 tó sì jẹ́ pé ní South Korea, wọ́n ṣe ìdádúró ètò ẹ̀kọ́ kan nígbà tí wọ́n ṣàwárí àwọn kùdìẹ̀kudiẹ kan nínú àwọn ìwé ìkẹ́kọ̀ọ́ tí wọ́n fi AI ṣe, tó sì lè ṣàkóbá fún ìlànà ìkẹ́kọ̀ọ́.[8]

## Àwọn Kókó Àrídìmú

- AI kìí ṣe ọ̀nà àbùjá láti ṣe àtúntò ìjọba. Láì sí àlàkalẹ̀ ìlànà ìṣàmúlò fún àtúntò, ohun èlò tó pójú owó àti ìlànà ìṣèjọba tó yé yéké, ṣíṣe àmúlò AI, ó ṣeé ṣe kí ìṣàmúlò rẹ̀ mú ìkúrẹtẹ̀ bá ètò ìṣejọba àti àìsí ìbòjútó pọ̀ si ju kí ó mú ìgbéga bá tàbí ṣíṣe tàbí òdodo lọ.
- Àṣeyọrí AI nínú ìjọba jẹ́ ìpèníjà fún ìṣèjọba kìí ṣe ti ìmọ̀ ẹ̀rọ. Àwọn àbájáde kò gbáralé bí ìmọ̀ ẹ̀rọ ṣe lágbára tó dípò bí àwọn ilé iṣẹ́ ṣe lágbára sí, àwọn ìlànà ìṣàfihàn, agbára àjọṣepọ̀ àwọn olùtajà, àti ìlànà ìfaradà.
- A ṣe àgbékalẹ̀ ìgbésẹ̀ mẹ́rin: ṣíṣe àtúntò àwọn ohun tí aráàlú ń lò lórí àwọn ìṣòro rẹ̀ gangan ṣáájú ṣíṣe àgbékalẹ̀ AI; ṣíṣe ìdókoòwò sí ṣíṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fáwọn òṣìṣẹ́ ní gbogbo ẹ̀ka, ṣàgbéyẹ̀wò agbára àwọn olùtajà láti ri pé àjọṣepọ̀ wà nípasẹ̀ rírà ọjà lápapọ̀ àti ìlò AI èyí tí aráàlú jẹ́ aṣojú rẹ̀ lábẹ́ àkóso kan èyí tí wọ́n gbé kalẹ̀ lórí ìṣàfihàn tòótọ́ àti àbójútó tó péye.

Èyí kò túmọ̀ sí pé kí ìjọba má gbìyànjú láti ṣàmúlò tàbí dán AI wò. Dídúró de ìgbà tí àwọn ewu tó rọ̀ mọ́ lílo AI máa dópin máa jẹ́ àṣìṣe ńlá, tó sì léwu: tí àwọn adarí ẹ̀ka ìjọba kò bá bẹ̀rẹ̀ sí ní lo AI láti mú àyípadà bá ìjọba báyìí, ìyàtọ̀ tó máa wà láàárín ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ ẹ̀ró láàárín ẹ̀ka ìjọba àti àwọn aládàni máa pọ̀ púpọ̀, tó sì lè pọnkún àìní ìgbàgbọ́ nínú pípójú owó àwọn iléeṣẹ́ ìjọba tí aráàlú ti ní tẹ́lẹ̀.

Àwọn ìjọba gbọdọ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní gbé ìgbésẹ̀ báyìí nípa ìrìnàjò AI, kí wọ́n sì kojú àwọn àlàfo àti àìsí ìmọ̀ kíkún tó ń dènà ṣíṣe àmúlò ìmọ̀ ẹ̀rọ ní àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba.

> ***"Ìrírí àwọn aráàlú nípa ètò ìṣèlú àwaarawa kìí ṣe lásìkò ètò ìdìbò nìkan, ó tún jẹ́ bí wọ́n ṣe ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àwọn ohun tó jẹ́ ti ìjọba sí. Tí kò bá sí ọ̀wọ̀, pínpin déédé, ìwà gbangba làṣá ń ta àti ìgbágbárawọni nínú ìbáṣepọ̀ náà, níní ìfọkàntán àti ojú táwọn aráàlú fi máa rí àwọn iléeṣẹ́ ìjọba kò le gbèrú."***[9]

## Ìpèníjà àkọ́kọ́
## AI le mú àlékún bá àìṣe déédé ìjọba

Àwọn ìṣòro òní kìí ṣe tuntun; láti ìgbà tí ètò ìṣèjọba pínpín ẹlẹ́kajẹ̀ka òde òní ló ti ń yọjú díẹ̀díẹ̀.

Ohun tí wọ́n ṣe ìdásílẹ̀ rẹ̀ fún ni láti ri pé ètò ìṣèjọba ń yí kan gbogbo ẹ̀ka lójúnà àti máa ṣe déédé lábẹ́ òfin, ètò ìṣèjọba yìí máa ń pèsè ààyè fún àìṣe déédé tó máa ń pọnkún kí àwọn aráàlú má nì í ìgbágbọ́ nínú àwọn iléeṣẹ́ ìjọba.

Àwọn òfin ìṣèlú tó le àti ṣíṣe àwáwí àwọn ìgbésẹ̀ ṣeéṣe kó bo pàtàkì ìgbésẹ̀ náà mọ́lẹ̀, nígbà tí ìgbésẹ̀ kò bá yá náà le mú kí ìṣèjọba má kẹ́sẹ járí.

Ní àkọ́ọ́lẹ̀, AI le ṣe ìrànwọ́ fún ìjọba láti kojú àwọn àìṣe déédé yìí nípasẹ̀ ṣíṣe àtúntò ọgbọ́n àtinúdá àti àwọn ìlànà tí wọ́n ń gbà. Síbẹ̀, ewu ńlá wà pé ìjọba máa pàdánù àǹfàní yìí tó bá jẹ́ pé àwọn ìlànà tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ ni ìjọba ń sáré láti lo AI fún dípò mímú ìgbéga bá wọn. Nípasẹ̀ fífi àwọn òfin tó ti wà tẹ́lẹ̀, iṣẹ́ tí kò lọ déédé àtàwọn ọgbọ́n inú tí ọjọ́ ti lọ lórí wọn sínú ìmọ̀ ẹ̀rọ AI, ìjọba yóò tún máa mú ìgbèrú bá àwọn àìṣe déédé tó ti wà tẹ́lẹ̀. Láì sí àyípadà tó ṣe kókó, àwọn ẹ̀rọ tuntun yìí yóò máa pèsè àìṣe déédé sí i dípò pípa àwọn èyí tó wà tẹ́lẹ̀ ré.

Bẹ́ẹ̀ náà ni AI kò ní jọ̀wọ́ àwọn àǹfàní rẹ̀ sílẹ̀ tó bá jẹ́ pé bú irinṣẹ́ kan bá ṣe wà n'lẹ̀ sí tàbí báwọn èèyàn bá ṣe ń lò ó sí bíi chatnots ló ń darí àwọn ìpinnu ìjọba. Àwọn àkànṣe iṣẹ́ tí wọ́n fi AI ṣe – tó sì ń jẹ́ ìkọnilóminú ní 2026 – ló ṣeéṣe kí wọ́n ṣàfihàn àwọn kùdìẹ̀kudiẹ àti àìkájú òṣùwọ̀n ìjọba lórí ètò ìṣejọba.[10]

## Ìgbésẹ̀ àkọ́kọ́
## Ìyípadà sí fífi ìṣòro mọ́ ìṣàmúlò AI, tó wà láti ìsàlẹ̀ lọ sókè

Ṣáájú lílo AI, àwọn ìjọba nílò láti ṣe àlàkalẹ̀ àwọn àǹfàní tí àkànṣe iṣẹ́ AI máa mú wá. Gbogbo iṣẹ́ tí wọ́n bá máa lò ó fún gbọdọ̀ pèsè àǹfàní fún aládàni, àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba àti ilé iṣẹ́ tó ń ṣàmúlò rẹ̀.[11] **Èyí túmọ̀ sí ṣíṣe ìdámọ̀ ohun táwọn èèyàn nílò tí àkànṣe iṣẹ́ náà máa kojú rẹ̀** (bí àpẹẹrẹ, ṣíṣe ìpinnu kíákíá, àwọn ìdájọ́ tó ṣe déédé jùlọ), ṣíṣe àgbéyẹ̀wò bóyá àwọn ohun èlò tó wà ní iléeṣẹ́ ní ìjọra láti kojú àwọn ìnílò náà àti láti ṣe ìdámọ̀ àwọn ohun tó ṣé é ṣe ìgbéléwọ̀n ipa rẹ̀ bí ìgbà bá ṣe ń lọ. Nígbà tí àtúntò bá ti bá àwọn ìlànà tí wọ́n sì lọ pẹ̀lú ohun tí aráàlú ń fẹ́ nìkan ló yẹ láti ṣe àmúlò wọn. A lè fi ìrírí United Kingdom gbé èrò yìí lẹ́sẹ̀: dípò gbígbé lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ kíákíá síwájú, wọ́n ṣe àtúngbéyẹ̀wò àwọn ohun tí aráàlú ń fẹ́ kí wọ́n tó gbé ìmọ̀ ẹ̀rọ síta láti fi máa pèsè wọn.[12]

> ***Àwọn ìjọba nílò láti bẹ̀rẹ̀ ìgbésẹ̀ lílo AI nípa kíkojú ìpèníjà ńlá tó ń dènà wọn láti lo AI lọ́nà àti fi ṣe àyípadà tòótọ́ – ìyẹn ni pé ni ọ̀nà tó máa jẹ́ kí lílo àwọn ohun tó wà fún aráàlú rọrùn láti ṣàmúlò, mú àdínkù bá ẹ̀rù ìjọba, mú àlékún bá ìṣàkóso, mú ìgbòrò bá ṣíṣe dọ́gba-ń-dọ́gba tàbí mú àlékún bá èsì tó dára fáwọn èèyàn.***

Láti mú àfojúsùn yìí wá sí ìmúṣẹ, àwọn ìjọba nílò láti jìnà sí gbígbé ìlànà ìmọ̀ ẹ̀rọ jáde nípasẹ̀ kí àwọn olórí kọ́kọ́ lò ó kó tó dé ọ̀dọ̀ àwọn aráàlú, ó yẹ kí wọ́n ṣiṣẹ́ pọ̀ pẹ̀lú àwọn tí yóò máa ṣe àmúlò rẹ̀ àtàwọn òṣìṣẹ́ ìjọba tó níiṣe pẹ̀lú aráàlú láti lè ri dájú pé wọ́n pèsè AI síbi tí wọ́n ti mọ iyì rẹ̀ jùlọ. **Ó yẹ láti gba àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ bí àwọn tó jọ máa ṣiṣẹ́ lórí rẹ̀** (dípò àwọn tó máa lò ó lásán) kí wọ́n sì ri pé wọ́n kópa nínú ìgbésẹ̀ náà láti ṣíṣe ìdámọ̀ àwọn ìṣòro àti àṣeyọrí títí tí wọ́n fi máa gbìyànjú rẹ̀ ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ àti bí wọ́n ṣe máa ṣàtúntò àwón ohun èlò àtàwọn ìlànà abẹ́nú. Ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ wọn, tó fi mọ́ èyí tí wọ́n ń lò láti fi tán ìṣòro àwọn èèyàn nígbà tí wọ́n kò bá sí lẹ́nu iṣẹ́ gbọ́dọ̀ ìṣàmúlò nígbà tí wọ́n bá ń ṣe àgbéjáde AI ní gbogbo ìpele.

**Ṣíṣe àmúlò AI yẹ kó bẹ̀rẹ̀ díẹ̀díẹ̀, pẹ̀lú kíkojú àwọn ìṣòro kan ní pàtó,** pẹ̀lú àmójútó nípa ipa wọn lórí iṣẹ́, ìṣe dọ́gbańdọ́gba àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn ìjọba yẹ láti ṣe àgbéjáde rẹ̀ lórí àwọn èyí tó bá ní àṣeyọrí, kí wọ́n pa èyí tí kò yege nù, kí wọ́n sì lo àwọn ẹ̀kọ́ tí wọ́n bá rí kọ́ níbẹ̀ láti fi ṣe àtìlẹ́yìn fún ìṣàmúlò rẹ̀ ní gbogbo ẹ̀ka àti àjọ ìjọba.

Denmark pèsè àpẹẹrẹ ìlànà àlékún yìí nípa lílo sandboxes àti ìlànà ipele ipele sí ṣíṣe àgbéjáde wọn.[13]

# Ìpèníjà kejì
# Àwọn ìjọba kò ní ilé iṣẹ́ tó ní ìkápa láti ṣe àmúlò AI

Ọ̀pọ̀ àwọn ìjọba ló ń kojú ìṣòro àìní ìkápá àtàwọn ilé iṣẹ́ tó le ṣàmúlò AI èyí tó ń káwọn lọ́wọ́ kò láti ṣe àkóso AI. Nígbà tí ara ìpènìjà tí wọ́n gbọdọ̀ kojú ń wọnú ara wọn síi, wọ́n ṣì ń ṣiṣẹ́ ní ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, tí wọ́n sì ń gbáralé àwọn dátà tí kò kájú òṣùwọ̀n, tí wọ́n sì ń ṣiṣẹ́ lábẹ́ òfin tó le èyí tó jẹ́ ìṣàkóso àwọn ilé iṣẹ́ àti àjọ ìjọba ṣòro. Èyí máa ń jẹ́ kí ìpinnu ìjọba pẹ́ kí wọ́n tó fèsì, tó sì máa ń dín agbára ìjọba kù lórí àwọn ètò rẹ̀.

Ní ìpele iṣẹ́, níní àǹfààní sí iṣẹ́ nílò ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìbáṣepọ̀ láàárín àwọn ilé iṣẹ́, àwọn ìlànà tó ti pẹ́ kò lè ṣe pàṣípààrọ̀ dátà tàbí ṣe àtìlẹ́yìn fún pípésè iṣẹ́ tó pójú owó, tí ṣíṣe ìpinnu tó dára máa ń jìyà, tí àwọn òṣìṣẹ́ tí iṣẹ́ ti pọ̀ fún sì ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú àwọn òfin tí kò báramu àti àìsí àwọn ìròyìn tó ṣe kókó.

Àwọn ìjọba tún dojúkọ àlàfo àìsí àwọn tó ní ìmọ̀ nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé láàárín àwọn olórí tó ń ṣe ìpinnu àti láàárín àwọn òṣìṣẹ́ tí wọ́n wà nídìí ṣíṣe àmúlò AI fún iṣẹ́ ṣíṣe.[14] Ẹ̀ka aládàni ni ó máa ń jẹ àǹfààní jùlọ nígbà tí wọ́n bá àwọn tó ní ìmọ̀ nípa níbi tí owó oṣù, ìyípadà àti ìlọsíwájú iṣẹ́ ti fani mọ́ra jùlọ. Nítorí náà, ọ̀dọ̀ àwọn olùtajà ni wọ́n máa fọkàn sí jùlọ dípò láàárín àwọn ìjọba fúnra wọn, èyí sì máa ń mú kí àwọn ènìyàn gbára lé wọn, tó sì ń ṣàkóbá fún bí àwọn aráàlú ṣe ń rí wọn.

# Ìgbésẹ̀ kejì
# Ṣíṣe ìgbéga nípa ìdánilẹ́kọ̀ọ́ àti ìpèsè ikọ̀ tó máa ṣe àtìlẹ́yìn fún àpapọ̀ AI

Àwọn ìjọba yóò ṣe àṣeyọrí ní mímú àwọn ipa rere AI pọ̀ si àti dín àwọn ewu rẹ̀ kù bí wọ́n bá rí i dájú pé àwọn olórí, àwọn òṣìṣẹ́ wọn, àti àwọn ilé-iṣẹ́ wọn ní agbára láti ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí àwọn olùdarí AI tó múnádóko.

Àkọ́kọ́, **àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ ṣe ìdábilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba láti lè ṣiṣẹ́ tó pójú owó pẹ̀lú àwọn irinṣẹ́ AI.** Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ètò ìdánilẹ́kọ̀ọ́ sábà máa ń tẹmpẹlẹmọ ìwà rere AI, àwọn òṣìṣẹ́ tún nílò àwọn ọgbọ́n àti ìgboyà láti lo AI dáadáa nínú iṣẹ́ ojoojúmọ́ wọn, bíi agbára láti mọ bí ó ṣe ń ṣiṣẹ́ ní àyíká kan, ṣe ìdámọ̀ ìgbà tí ètò kan bá ṣeé ṣe kí ó kùnà, àti láti ṣe àmúlò àti ìlànà tó ṣe é gbáralé nígbà tí ìfàséyìn bá wáyé. Àwọn ìgbésẹ̀ tí a gbé kalẹ̀ tó sì ń tẹ̀síwájú gbọ́dọ̀ jẹ́ àmúṣẹ láti ran àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba lọ́wọ́ láti ní àwọn ìmọ̀ tí ó yẹ láti ṣe àwọn iṣẹ́ tó jẹ́ pé ènìyàn nìkan lè ṣe, bíi ìtumọ̀ àwọn ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tó le, ṣíṣe ìgbéléwọ̀n àwọn èrò tó lè jọ ara wọn, àti ríri dájú pé àwọn ìpinnu algoridimu jẹ́ òdodo.

> ***"Láti lo àǹfààní "àwọn ohun èlò ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ, o máa nílò láti mú àgbéga bá ìmọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ rẹ [. . .]. Nígbà tí ìmọ̀ ẹ̀rọ bá ṣe àwárí ìwà jìbìtì tàbí tó wòye pé oníbàárà tàbí òṣìṣẹ́ le ní ìjákulẹ̀ tí ìwòye náà sì péye pẹ̀lú ìdá àádọ́rùn-ún (90%), àwọn ènìyàn gbọ́dọ̀ kojú ìdá mẹ́wàá (10%) tó kù fúnra wọn - ìyẹn ni yóò sì jẹ́ ìdá mẹ́wàá (10%) tí ó le jùlọ."***[15]

Èkejì, **ìjọba kọ̀ọ̀kan gbọ́dọ̀ ronú láti ṣe ìdásílẹ̀ ikọ̀ tí yóò máa ṣe àtìlẹyìn fún ìṣàmúlò lílo àpapọ̀ AI** láti ṣèrànwọ́ fáwọn ilé iṣẹ́ ìjọba lọ́wọ́ láti ṣàmúlò AI lọ́nà tó dára. Àfojúsùn ikọ̀ yìí ni láti máa ṣe àtìlẹyìn fún àwọn iléeṣẹ́ àti àjọ ìjọba ní gbogbo ìgbà tí wọ́n bá fi ń ṣàmúlò AI, láti ṣe ìdámọ̀ àwọn tí lílo rẹ̀ níye lórí àti ṣíṣe àtúntò àwọn iṣẹ́ ṣíṣẹ́ kí a tó ṣe àtúnṣe sí àgbékalẹ̀, yíyan àti síso àwọn irinṣẹ́ tó yẹ pọ̀ nígbà tí wọ́n ń rí i dájú pé wọ́n tẹ̀lé àwọn ìlànà òfin tàbí ààbò tó yẹ. Àwọn iṣẹ́ tó ṣe kókó rẹ̀ ni: ṣíṣe àyẹ̀wò bó ṣe le ṣiṣẹ́ sí àti àwọn ewu tó rọ̀ mọ́; ṣíṣe àwọn ìlànà tó wọ́pọ̀ fún dídára dátà, ìṣàkóso àwòṣe, àti àkọsílẹ̀; ṣíṣe àyẹ̀wò àwọn tí wọ́n fi bẹ̀rẹ̀ àti gbígbé ìgbésẹ̀ nígbà tí àwọn ètò AI bá nílò àtúntò tàbí yíyọ wọn kúrò. Àkójọpọ̀ rẹ̀ yẹ kí ó ṣàfihàn ìgbésẹ̀ yìí nípa síso ìmọ̀ ẹ̀rọ, òfin, ètò ìṣèlú, iṣẹ́ ṣíṣe, àti ìṣàkóso ìyípadà papọ̀, títí kan àwọn ìmọ̀ nínú òfin ìṣèlú, ṣíṣe àgbékalẹ̀ àwọn ètò tó fi ọmọnìyàn síwájú.

# Ìpèníjà Kẹta
# Àwọn ìjọba dojúkọ àìdọ́gba agbára ńlá

Jíjára mọ́ mímú ìdàgbàsókè bá AI ti yí ìwọ̀n agbára padà láàárín àwọn ìjọba àti ẹ̀ka aládàni, èyí tí ó ń pe ìjọba àti ìṣàkóso tiwantiwa níjà. Àwọn olùtajà AI, tí wọ́n jẹ́ ẹgbẹ́ kékeré ilé-iṣẹ́ Améríkà àti China, máa ń ṣe àkóso bí àwọn èèyàn ṣe ń ní àǹfààní sí ìmọ̀ ẹ̀rọ, tí wọ́n sì ń ṣàkóso ìròyìn, àwọn àdéhùn, àti àwọn òfin iṣẹ́, èyí tí ó máa jẹ́ kí ìjọba gbáralé wọn fún àwọn ohun tó ṣe kókó bíi ṣíṣe àkójọ èrò, àwọn ohun èlò ìmọ̀ ẹ̀rọ tó nííṣe pẹ̀lú kíkó nǹkan pamọ́, àwọn àwòṣe èdè ńlá, àti àwọn onímọ̀ ìjìnlẹ̀ tí wọ́n nílò láti fi ṣe ìgbéjáde àwọn irinṣẹ́ AI láàárín àwọn ilé iṣẹ́ àti àjọ ìjọba.[16]

Ìgbẹ́kẹ̀lé yìí kìí ṣe ìṣòro lásán; ó ti di ìkúrẹtẹ̀ fún òṣèlú. Àwọn ìjọba kìí sábà ní àǹfààní sáwọn àkọ́ọ̀lẹ̀, àwọn àyẹ̀wò, tàbí àlàyé nípa bí wọ́n ṣe ń ṣiṣẹ́ sí, tí wọ́n sì nílò láti gbáralé àyẹ̀wò àwọn olùtajà láti ṣe àyẹ̀wò àwọn ètò AI tí ó ní ipa lórí àwọn ẹ̀tọ́ àwọn èèyàn. Nígbà tí ilé iṣẹ́ ìjọba kò bá lè ṣe àyẹ̀wò àwọn irinṣẹ́ tí ó ń lò láti pinnu àwọn tó yẹ láti gba ẹ̀tọ́ kan, tàbí nígbà tí àwọn àdéhùn ìpamọ́ bá dí àyẹ̀wò àwọn irinṣẹ́ ohun èlò ààbò lọ́wọ́, ó túmọ̀ sí pé àwọn aláṣẹ rẹ̀ ń ṣàkóso ní òkùnkùn.

Ríra ọjà ń mú kí àìdọ́gba agbára wọ̀nyí pọ̀ sí i. Ọ̀pọ̀ àwọn ìjọba kò ní agbára láti ṣe ìdúnàádúrà ẹ̀tọ́ wọn lórí àyẹ̀wò, láti béèrè fún gbangba làṣá ń ta, tàbí láti dènà àwọn olùtajà, èyí tí ó ń yọrí sí ìgbẹ́kẹ̀lé ìgbà pípẹ́. Orí àwọn orílẹ̀-èdè kéékèèké ni èyí máa ń já lé lórí jùlọ, tí wọ́n kò ìkápa láti gbé ìlànà kalẹ̀ tí ìwọ̀n wọn níbi àwọn tó ń gbé ìlànà kalẹ̀ sì kéré jọjọ.

Bí àwọn ilé iṣẹ́ káàkiri àgbáyé ṣe ń ṣe àgbékalẹ̀ àwọn òfin sí báwọn èèyàn ṣe ń ní àǹfààní sí àwọn ètò AI tí ó ti ní ìlọsíwájú, àwọn ìjọba wà nínú ewu láti di ẹni tó ń gba ní àwọn ipò tó súnmọ́ ṣíṣe àkóso orílẹ̀-èdè. Láìsí ọgbọ́n àtinúdá láti gba àbójútó padà, àwọn irinṣẹ́ tí wọ́n mú ìgbèrú bá láti mú kí ìṣàkóso ètò ìṣèjọba rọrùn ló ṣeéṣe kó di ohun tó máa mú ìkúrẹtl bá agbára wọn láti ṣe bẹ́ẹ̀.

# Ìgbésẹ̀ Kẹta
# Fífi agbára aráàlú hàn nípa àjọṣepọ̀ àti agbára ìmọ̀ ẹ̀rọ

Láti gba agbára ìṣàkóso AI fún lílò rẹ̀ nínú àkóso ìṣèjọba, àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ kọ́kọ́ yípadà láti ríra ọjà tí a yà sọ́tọ̀ sí ìgbésẹ̀ tí a ṣètò. **Àjọṣepọ̀ ríra ọjà,** bíi ìjíròrò àpapọ̀ tí wọ́n lò fún àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára,[17] máa jẹ́ kí àwọn ìjọba tó ń kópa láti kó àwọn tó nílò ìmọ̀ rẹ̀ àtàwọn onímọ̀ ìjínlẹ̀ nípa rẹ̀ jọ. Àkójọpọ̀ yìí máa ṣe ìrànwọ́ fún wọn láti jẹ́ kí wọ́n lè rí ohun tí wọn kò lè rí gbà láwọn nìkan tó fi mọ́ ẹ̀tọ́ àyẹ̀wò tó ní ìtumọ̀, àfihàn iye ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tòótọ́, àkọsílẹ̀ nípa ohun èlò tí wọ́n fi bẹ̀rẹ̀, àti ìdánilójú ṣíṣe ìyípadà dátà lóòrè kóòrè. Nígbà tí ọ̀pọ̀ àwọn ìjọba bá ṣe ìdúnàádúrà pẹ̀lú olùtajà kan, ohun tí bá jẹ́ “àìṣe déédé”le padà di ohun àfojúsùn.

Àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba tún yẹ kí wọ́n **fọwọ́sowọ́pọ̀, ní orílẹ̀-èdè wọn àti ní àgbáyé, nípa ṣíṣẹ̀dá àti pínpín àwọn irinṣẹ́ AI, àwọn àwòṣe, àwọn àwòṣe ìwé-àṣẹ, ìtọ́sọ́nà ààbò, ìmọ̀ òfin àti ìmọ̀ ìjìlẹ̀ nípa ìṣèjọba, tàbí àgbéyẹ̀wò àwọn ìjábọ̀.** Irú ọ̀nà bẹ́ẹ̀ (pàápàá àjọṣepọ̀ àpapọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè àti àarin gbùngbùn gúúsù South-South láti ṣẹ̀dá àwọn ẹgbẹ́ ìrànlọ́wọ́ ní àpapọ̀ tàbí ní ọkùn kọ̀ọ̀kan) yóò jẹ́ kí wọ́n àtúnlò àti àtúnṣe àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ tí ó ṣeé gbẹ́kẹ̀lé láìsí ìyípadà sí àwọn ètò tó ti wà tẹ́lẹ̀. Àwọn dúkìá ìmọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé tí ìjọba tó wà fún gbogbogbò lè dín ìgbẹ́kẹ̀lé àwọn ìjọba lórí àwọn olùpèsè láti òde kù. Bí àpẹẹrẹ, X-Road, ìpele ìbáṣepọ̀ àti ìyípadà dátà tí Estonia ń darí, ń jẹ́ kí àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba àti àwọn olùpèsè tí a fún ní àṣẹ láti bá ara wọn sọ̀rọ̀ nípasẹ̀ àwọn ibi ìpamọ́ dátà tó ṣe déédé, dípò àwọn ìpele ayé àtijọ́, tí àwọn orílẹ̀-èdè tó ogún tó fi mọ́ Finland, Ukraine, àti Japan ló ti ń ṣàmúlò rẹ̀ báyìí.[18]

Fífi àṣẹ ìjọba múlẹ̀ lórí ìṣàmúlò AI kò túmọ̀ sí ṣíṣe ètò ìgbàlódé lábẹ́nú. Ìmọ̀-ẹ̀rọ tó dá dúró náà ní

àwọn ewu tirẹ̀, tó fi mọ́ àtúnṣe tó lọ́ra, àìsí àǹfààní láti ní agbára ìlọsíwájú, àti ìkùnà nínú ìjọba fúnra rẹ̀. Dípò bẹ́ẹ̀, níní ìfaradà ìmọ̀ ẹ̀rọ nílò **rírí dájú pé kò sí ìmọ̀-ẹ̀rọ kan ṣoṣo, olùtajà, tàbí àwòṣe ilé iṣẹ́ kan ṣoṣo di ohun tó ṣe pàtàkì, tí kò ṣeéṣe pẹ̀lú.** Ohun tí a nílò ìwòye ìmọ̀ ẹ̀rọ ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì. Bí àpẹẹrẹ, ṣíṣe àgbékalẹ̀ ohun èlò ìgbàlódé tó jẹ́ ti gbogbogbò sí ìkápá àti ìpele ẹ̀ka aládàni, lílo àwọn olùpèsè ọjà tó pọ̀, díènà gbígbé ara lé ojú òpó kan ṣoṣo àti rírí dájú pé àwọn ètò náà ṣe é gbé kiri ní gbogbo ojú òpó. Ọ̀nà tí India gbà ṣe àfihàn ọgbọ́n yìí, pẹ̀lú bí wọ́n ṣé ń ṣàkóso àwọn ohun èlò ìgbàlódé ti ìjọba pẹ̀lú àwọn olùpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ nípasẹ̀ ojú òpó ẹ̀ka aládàni.

***Ìbéèrè tó ṣe kókó fún àwọn ìjọba kìí ṣe bóyá kí wọ́n gbáralé ọjà tàbí kí wọ́n kọ́ ohun gbogbo fúnra wọn, bí kò ṣe bí a ṣe lè ṣàkóso àwọn ètò ìdàpọ̀ lọ́nà tí yóò pa agbára ìfaradà, àti ìṣàkóso ìgbà pípẹ́ mọ́.***

## Ìpèníjà Kẹrin
## Àìsí ìfihàn tóòtọ́ ń mú káwọn aráàlú má nì í ìgbàgbọ́ nínú àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba

Lọ́pọ̀ ìgbà ni wọ́n máa ń ṣe ìfilọ́lẹ̀ AI láì ṣe àwọn ohun tó yẹ láti ri dájú pé lílò rẹ̀ pé èyí tó máa jẹ́ kí ó tẹ̀síwájú àt láti lè jẹ́ káwọn aráàlú ní ìgbàgbọ́ nínú àwọn iléeṣẹ́ ìjọba. Irú èyí le wáyé nígbà tí wọ́n bá ṣe àgbéjáde AI láìsí ìjíròrò pẹ̀lú aráàlú tàbí ètò ìṣòfin láti fi òǹtẹ̀ lù ú, táwọn èèyàn tí ọ̀rọ̀ kàn kò mọ bí wọ́n ṣe ṣàgbékalẹ̀ tàbí mọ̀ pé wọ́n ń lo ìmọ̀ ẹ̀rọ kan. Àwọn òfin tí wọ́n là kalẹ̀ kedere lórí ìwàn gbangba làṣá ń ta máa ń jẹ́ láti dá ààbò bo àwọn ohun ìní wọ̀nyí.

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn AI tí àwọn ìjọba ń lò ni kìí jẹ́ ohun tó ṣe é mọ̀ nípa rẹ̀ dáadáa, èyí tó máa ń jẹ́ kó nira fún àwọn èèyàn tó fi mọ́ àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba láti má nì í ìmọ̀ kíkún nípa bí ìpinnu ṣe ń wáyé. Lábẹ́nú, ọ̀pọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba ló ṣeéṣe kí wọ́n máa yíjú ṣíṣe ìpinnu pẹ̀lú ìrànwọ́ AI láìsí ìmọ̀ kíkún nípa lílò rẹ̀ èyí tó le mú kí wọ́n gbáralé ìmọ̀ràn ìmọ̀ ẹ̀rọ láìsí ìgbéléwọ̀n ti àwọn èèyàn. Bí àpẹẹrẹ, iléeṣẹ́ ọlọ́pàá Spain tẹ̀lé àwọn ìmọ̀ràn tí AI fún wọn nípa gbígbógun ti ìwà ipá tó ní ṣe pẹ̀lú abo nínú ó kéré tán ìdá márùndínlọ́gọ́rùn-ún (95%) àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ dípò kí wọ́n lò ó  gẹ́gẹ́ bí ọ̀kan lára àwọn ọ̀nà tí wọ́n le gbà.[19]

Èyí jẹ́ ìṣòro nítorí pé àwọn ènìyàn kìí sábà ní ọ̀nà tó pọ́jú láti tako àwọn ìpinnu tí wọ́n ń fi AI ṣe àtìlẹyìn fún èyí tó ń ní ipa lórí wọn. Báyìí, àwọn orílẹ̀-èdè mẹ́ẹ̀ẹ́dọ́gbọ̀n péré ló ní àwọn ìlànà tí ó ń pèsè àtúnṣe àti ọ̀nà àtúnṣe níbi tí ètò AI tí ìjọba ń darí ń ní ipa búburú lórí àwọn ènìyàn.[20] Èyí tí ó burú jù ni pé, ọ̀pọ̀ ènìyàn káríayé kò ní ìmọ̀ tó yẹ láti mọ̀ nígbà tí AI bá wà nínú ìpinnu kan, ká má tilẹ̀ sọ pé kí wọ́n lóye, béèrè ìbéèrè, tàbí tako àwọn àbájáde rẹ̀. Ní àwọn orílẹ̀-èdè kan bíi South Africa, níbi tí ìdá méjì nínú mẹ́ta àwọn ènìyàn kò tíì gbọ́ nípa AI rí tàbí ní òye díẹ̀ nípa ohun tí ó jẹ́ tàbí bí ó ṣe lè ní ipa lórí ìgbésí ayé wọn,[21] kò ṣeé ṣe kí wọn tako àwọn ìpinnu tí AI ń ṣe ìrànlọ́wọ́ fún láti jẹ́ ṣíṣe àmúlò.

***Gẹ́gẹ́ bí ìwádìí UN kan, àwọn orílẹ̀-èdè tí wọ́n dáhùn sí ìbéèrè yìí tí wọ́n ń ṣe àtúnṣe sí òfin tàbí ìlànà lórí lílo AI bí ó ṣe tọ́ nínú àwọn ètò ìṣèjọba ni ó kéré díẹ̀ sí ìdajì àpapọ̀ àwọn orílẹ̀ èdè náà.***[22]

## Ìgbésẹ̀ Kẹrin
## Jíjẹ́ kí àwọn aráàlú ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú AI

Dípò kí gbígbẹ́kẹ̀lé ààbò tó yàtọ̀, àwọn ìjọba yẹ láti ṣe ìdásílẹ̀ ìlànà tí yóò máa rí sí báwọn aráàlú ṣe le máa ní ìfọkàntán nínú AI láti ṣe ìtẹnumọ́ agbára táwọn èèyàn ní lórí àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ AI àti ìgbẹ́kẹ̀lé táwọn èèyàn àti àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba ní nínú wọn. Ní pàtàkì, ìlànà yìí kò gbọdọ̀ jẹ́ ohun tó máa yàtọ̀ sáwọn ìlànà òfin tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀ ṣùgbọ́n kí ó ní ìsopọ̀ pẹ̀lú òfin tó de ìṣàkóso, àwọn òfin rírà tó rọrùn, àti ìlànà kan pàtó fún

AI tí wọ́n ń ṣàmúlò, èyí tó ti pèsè àwọn ohun èlò fún lílo AI nínú ìṣèjọba ní àwọn ẹ̀ka tó jẹ́ ti aráàlú. Àkọ́kọ́, níní ìfọkàntán nílò ìwà gbangba làṣá ń ta láti fẹsẹ̀ rinlẹ̀ nípa mímú lílo AI jẹ́ ohun tó hàn, tí ó yéni, tí ó sì ṣí sílẹ̀ fún àyẹ̀wò. Orílẹ̀ èdè Canada ti fihàn pé àwọn ìjọba lè jẹ́ àwòkọ́ṣe nípa mímú ṣíṣe àwọn ìforúkọsílẹ̀ AI ní dandan – ṣíṣe àkọ́ọ́lẹ̀ gbogbo àwọn ètò ìjọba tó ń lo AI, ohun tí wọ́n ń lò wọ́n fún, bí wọ́n ṣe ń gba ìròyìn, àti bí ìkápá wọn ṣe mọ.[23] Àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba tún gbọdọ̀ máa ṣe

ìgbéléwọ̀n ipa tí irinṣẹ́ AI kan ní kí wọ́n tó máa gbe síta fún lílò, kí wọ́n sì máa fi àbọ̀ ìwádìí wọn hàn ní gbangba fún gbogbo aráàlú. Bákan náà ló yẹ kí wọ́n sọ fún àwọn aráàlú nígbà tí wọ́n bá lo irinṣẹ́ AI láti fi pèsè iṣẹ́ kan, kí wọ́n sì ṣàlàyé rẹ̀ lọ́nà tó máa yéni dáadáa ọ̀nà tí wọ́n gbà lo irinṣẹ́ náà.

Níní ìfọkàntán tún máa ń gbáralé àwọn ìlànà tí wọ́n ń gbà yanjú aáwọ̀ láti fi pín iṣẹ́ nípa lílo AI àti láti ri dájú pé ṣíṣe ìṣirò jẹ́ ohun tí wọ́n yóò ṣe àmúṣe rẹ̀ dójú àmì. Ní títẹ̀lé àpẹẹrẹ ti France, àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ ṣe àgbádìde àlàkalẹ̀ ìlànà (tàbí kí wọ́n mú ìgbòòrò bá àwọn tó ti wà nílẹ̀ tẹ́lẹ̀) bíi ẹni tó máa dàbí alárinà tàbí ṣe ìdásílẹ̀ ẹ̀ka tó máa ma gbọ́ ẹ̀hónú àwọn èèyàn, tí wọ́n sì máa ma wá ojútùú sí ìṣòro tó bá ṣúyọ.[24] Ní títẹ̀lé àpẹẹrẹ ti ìpínlẹ̀ Schleswig-Holstein ní Germany, wọ́n lè tẹ̀síwájú nípa ṣíṣe ètò "ìtakò AI" tí ó fi ààyè gba èèyàn láti ṣe àtúnṣe àti àtúngbéyẹ̀wò ìpinnu tó wọ́n ti pèsè sílẹ̀ tẹ́lẹ̀ láìsí àwọn àléébù kankan fún lílòdì sí ìpinnu náà.[25] Ní ṣíṣe àwọn ìlànà wọ̀nyí, àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ ṣe ìpinnu àti ètò tó dá lórí AI gẹ́gẹ́ bí South Korea ṣe ṣe láìpẹ́ yìí nípa ṣíṣe àlàyé báwọn ìlànà yìí ṣe ń ṣiṣẹ́ fáwọn ilé iṣẹ́ àtàwọn àjọ tó jẹ́ ti ìjọba.[26]

Nípari, níní ìfọkàntán máa ń jẹ́ ìmúdúró nípasẹ̀ àbójútó àwọn ìlànà ọlọ́pọ̀ àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ (àwọn ẹgbẹ́ tí wọ́n ní àṣojú láti ọ̀dọ̀ àwọn ajàfẹ́tọ̀ọ́ ọmọnìyàn, ètò ẹ̀kọ́, ilé-iṣẹ́, àti àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́) tí a gbé kalẹ̀ fún ṣíṣe àkóso, àgbéyẹ̀wò, àti ìgbéga sí àwọn ètò ìṣiṣẹ́ AI nígbà gbogbo. Láti ṣàtìlẹyìn fún ètò àbójútó tí wọ́n bá gbé kalẹ̀, àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ rí i dájú pé àwọn tó ń ta ìjọba ní olobó àti àwọn olùwádìí tí wọ́n ń ṣàwárí ìkùnà ètò tàbí ìrúfin ìwà rere ni wọ́n ń dá ààbò tó péye bò.

## Ààtò ìfọkàtán AI fún àwọn aráàlú

**Ipele gbígba àkọ́ọ́lẹ̀**
Ṣíṣe àfihàn gbangba àti fífi tó aráàlú létí
Níní àkọ́ọ́lẹ̀ tó hàn, ìwé àkójọ AI àti ṣíṣe àgbéyẹ̀wò ipa.

**Ipele yíyanjú aáwọ̀**
Agbára láti díje àtàwọn àtúnṣe tó múnádóko
Àwọn ìlànà àtúnṣe, ẹ̀tọ́ láti pe àwọn ìpinnu níjà, àti òfin lórí ìwà gbangba làṣá ń ta.

**Ipele Àbójútó**
Èyí tó ń tẹ̀síwájú, àkójọpọ̀, tí ó sí dá dúró
Ṣíṣe àbójútó lílo AI ti ìjọba látowọ́ àpapọ̀ àwọn alẹ́nulọ́rọ̀ àti dídá ààbò bo àwọn tó ń ta ìjọba olólobó.

## Àgbékalẹ̀ fún ìjákulẹ̀: ṣíṣe ìmúdóró ìṣiṣẹ́ AI

Ìjákulẹ̀ ìmọ̀ ẹ̀rọ lè yọrí sí ìdádúró àwọn iṣẹ́ tó ṣe kókó àti ìdènà pípèsè àwọn ohun èèlò, èyí tó le fa àwọn ipa tí ó le koko. Ní ọdún 2024, àtúnṣe tí kò dára tí ilé iṣẹ́ ìpèsè ààbò orí ayélujára CrowdStrike ṣe ṣokùnfà ìjákulẹ̀ ètò Windows mílíọ̀nù mẹ́jọ ààbọ̀ (8.5m) káàkiri àgbáyé, èyí sì ní ipa lórí àwọn ilé ìwòsàn, àwọn ẹ̀ka tó ń mójútó ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì, àti àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba.[27] Ní ọdún 2025, ìjàmbá iná kan tó wáyé ní ilé iṣẹ́ tó ń pèsè àkọ́ọ́lẹ̀ ní Korea ìyẹn Korea's National Information Resources Service ṣokùnfà ìjákulẹ̀ àwọn ètò ìjọba 647 tí kò sì jẹ́ kí àwọn aráàlú ní àǹfààní sí àwọn ètò pàtàkì fún ọ̀sẹ̀ mélòó kan.[28]

Níwọ̀n ìgbà tó ṣe pé kò ṣe é ṣe kí kùdìẹ̀kudiẹ̀ má kankan má wáyé, àwọn ìpèníjà gbòògì tí ìjọba ni agbára wọn, ìyẹn ni agbára wọn lórí bí wọ́n ṣe le gba ìdènà àti bí wọ́n ṣe lè tètè padà bọ̀ sípò kíákíá nígbà tí wọ́n bá ṣẹlẹ̀. Síbẹ̀, àwọn ìyípadà tó máa ń wáyé lágbo òṣèlú máa ń gbájúmọ̀ àwọn ìyípadà tó fojúhàn ju kí wọ́n gbáradì lọ, èyí tí kìí jẹ́ kí wọ́n ṣe àgbéyẹ̀wò, parí tàbí dán ìlànà àti padà bọ́ sípò wò. Ní àfikún, ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ìjọba ló máa ń gbára lé àwọn olùpèsè ìmọ̀ ẹ̀rọ, àwọn ibi ìpamọ́ dátà, àwọn olùpèsè AI pérété tó jẹ́ pé ìkọlù lórí ayélujára tàbí àjálù kékeré kan lè jẹ́ kó ní ìjákulẹ̀.

Láti dènà ìṣòro ìlànà, **àwọn ìjọba gbọ́dọ̀ rí agbára ìfaradà gẹ́gẹ́ bí èyí tó pàtàkì, tó fi mọ́ àwọn èyí tí wọ́n le fọkàn tẹ̀ nígbà tí ìjákulẹ̀ bá wáyé àti ṣíṣe ìdánwò bí iṣẹ́ bá pọ̀ sí.**

# Bẹ̀rẹ̀ kékeré. Gbéwọ̀n sókè. Ní ìfaradà.

Níwọ̀n ìgbà tó jẹ́ pé ohun tó wà tẹ́lẹ̀ ni AI máa ń mú àtúnṣe sí, ẹ̀hún ìpìlẹ̀ tó péye, tó sì dúró jẹ́ ohun ìnílò láti ṣàtìlẹyìn fún ìyípadà rẹ̀. AI yóò lè pèsè ohun táwọn aráàlú ń fẹ́ láti wá ojútùú sí ìṣòro táwọn tó ń ṣe àmúlò rẹ̀ nílò, èyí tó kún fún àtúnṣe àyíká, táwọn òṣìṣẹ́ tó pójú owó ṣe, tí ó rí àtìlẹyìn ìjọba, táwọn aláṣẹ sì ń ṣe àkóso rẹ̀ láìsí kọnú n kọ́họ

kankan nínú. Ó máa jẹ́ kí ìjákulẹ̀ yá dípò mímú àtúnṣe bá àwọn ìṣòro tí wọ́n bá ṣe ìgbéjáde lílò rẹ̀ nínú ìṣèjọba tó bá kún fún ìgbésẹ̀ tó mẹ́hẹ, àìdókoòwò sáwọn èèyàn bó ṣe yẹ, àìsí àkóso tó mọ́yán àti ìṣirò tí ò kájú òṣùwọ̀n.

Yíyẹra fún ìjákulẹ̀ túmọ̀ sí dídènà àdánwò fi AI rọ́pò mímú ìgbòòrò bá àwọn ilé iṣẹ́ àti ìdájọ́ tó sì jẹ́ lílo ìmọ̀ ẹ̀rọ náà láti fi mú ìgbéga bá wọn. Gbígbé ìgbésẹ̀ ní ṣíṣẹ̀-n-tẹ̀lé nígbà tí èèyàn bá ṣe ohun tí ọkàn rẹ̀ yàn láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ kò yẹ kó jẹ́ ohun ìtìjú tàbí àìle ṣe ìpinnu ṣùgbọ́n àmì ìjẹ́pàtàkì àti ẹni tó ní nǹkan ṣe.

Àwọn AI tí wọ́n kọ́kọ́ fara balẹ̀ ṣe, gbé jáde ní ìpele ìpele, àti mímúra sílẹ̀ fún ìjákulẹ̀ tó burú tó le wáyé jẹ́ ọ̀nà tó dára láti fi kẹ́kọ̀ọ́, fi ìníyelórí àwùjọ hàn àti láti ṣàtúnṣe síi kí àwọn ewu tí ó lè débá AI tó wáyé síi. Kò ì tíì dájú bóyá AI máa ṣe àyípadà sáwọn ìlànà ìṣèjọba wa tàbí pé ó máa jẹ́ ìmọ̀ ẹ̀rọ tó lágbára tó máa wà fún ìgbà pípẹ́ èyí tó le padà ní ìjákulẹ̀ lọ́jọ́ iwájú. Ohun kan tó dájú ni pé: **ṣíṣe àfihàn rẹ̀ bó ṣe yẹ ni ó máa jẹ́ owó fún ìṣàmúlò AI fún ìṣákóso aráàlú.** Láìsí ìlànà àti ààtò tó tọ́nà, àwọn ìjọba yóò padà ṣàwárí rẹ̀ pé àwọn ń lo ìmọ̀ ẹ̀rọ tí wọn kò lè ṣàkóso rẹ̀ àtàwọn aráàlú tó ń fi ojoojúmọ́ má nì í ìgbàgbọ́ nínú wọn.

## Notes


1. See OECD. (2025, September 18). *Governing with artificial intelligence*. https://doi.org/10.1787/795de142-en
2. Karadeglija, A. (2025, December 12). *Ottawa is using AI to review public comments on its national AI strategy*. Canada's National Observer. https://www.nationalobserver.com/2025/12/12/news/ottawa-using-ai-review-public-comments-its-national-ai-strategy
3. Government Technology Agency (GovTech) Singapore. (n.d). *AIBots*. https://www.tech.gov.sg/products-and-services/for-government-agencies/productivity-and-marketing/aibots/
4. OECD. (2025, September 18). *Governing with artificial intelligence*. https://doi.org/10.1787/795de142-en
5. See for example Wingar, J. (2025, March 10). *Musk Replacing Workers with AI: Should you Be Worried?* Forbes. https://www.forbes.com/sites/jasonwingard/2025/03/10/musk-replacing-workers-with-ai-should-you-be-worried/. Albania even experimented with an AI Minister but the developers have been accused of corruption; and the AI trained on unreliable data was overlooking some evidence. See: Jakes, L. (2026, January 27). *Albania Created an 'A.I. Minister' to Curb Corruption. Then Its Developers Were Accused of Graft*. New York Times. https://www.nytimes.com/2026/01/27/world/europe/albania-ai-corruption-graft.html
6. OECD. (2025, September 18). *Governing with artificial intelligence*. https://doi.org/10.1787/795de142-en. See also: Challapally, A., Pease, C., Raskar, R., & Chari, P. (2025, July). The GenAI divide: State of AI in business 2025. MIT. https://www.artificialintelligence-news.com/wp-content/uploads/2025/08/ai_report_2025.pdf
7. De Liban, K., & Marwick, A. (2024, December 10). *AI can't solve government waste – and may hurt vulnerable Americans*. Tech Policy Press. https://www.techpolicy.press/ai-cant-solve-government-waste-and-may-hurt-vulnerable-americans
8. Kwon, J. (2025, October 15). *AI powered textbooks fail to make the grade in South Korea*. Rest of World. https://restofworld.org/2025/south-korea-ai-textbook/

9. Parker, I. (2025, April 29). *Why public legitimacy for AI in the public sector isn't just a 'nice to have.'* Global Government Forum. https://www.globalgovernmentforum.com/why-public-legitimacy-for-ai-in-the-public-sector-isnt-just-a-nice-to-have/
10. Dizikes, P. (2024, December 6). *Daron Acemoglu: What do we know about the economics of AI?* MIT News. https://economics.mit.edu/news/daron-acemoglu-what-do-we-know-about-economics-ai
11. See Martinsuo, M. (2020). *The management of values in project business: Adjusting beliefs to transform project practices and outcomes*. Project Management Journal, 51(4), 389–399. https://doi.org/10.1177/8756972820927890
12. Government Digital Service & Central Digital and Data Office. (2025, April 2). *Government design principles*. https://www.gov.uk/guidance/government-design-principles
13. Danish Agency for Digital Government. (n.d.). *Danish strategies for artificial intelligence*. https://en.digst.dk/digital-governance/new-technologies/danish-strategies-for-artificial-intelligence
14. OECD. (2025, September 18). *Governing with artificial intelligence*. https://doi.org/10.1787/795de142-en
15. Ross, J. (2017, July 14). *The fundamental flaw in AI implementation*. MIT Sloan Management Review. https://sloanreview.mit.edu/article/the-fundamental-flaw-in-ai-implementation/
16. World Bank Group. (2025). *Digital development progress and trends report 2025: Strengthening AI foundations*. https://documents.worldbank.org/en/publication/documents-reports/documentdetail/099112525160593874
17. See: Gavi, the Vaccine Alliance. (2024). https://www.gavi.org/
18. See e-Estonia. (n.d.). *X Road: Interoperability services*. https://e-estonia.com/solutions/interoperability-services/x-road and Digital Cooperation Organization. (2025). *Digital public infrastructure: A key building block for social inclusion and economic development*. https://dco.org/wp-content/uploads/2025/06/DPI-Policy-Paper.pdf?ref=breakthroughpursuit.com
19. Satariano, A., & Toll Pifarre, R. (2024, July 18). *An algorithm told police she was safe. Then her husband killed her*. The New York Times. https://www.nytimes.com/interactive/2024/07/18/technology/spain-domestic-violence-viogen-algorithm.html.
20. *Global Index on Responsible AI*. (2024). https://agatadata.com/wp-content/uploads/2024/11/Global-Index-on-Responsible-AI-2024-Corrected-Edition-25_10_24-Gobierno-de-Canada-y-USAID.pdf
21. Junck, L. D., & Adams, R. (2025, September 29). *One in three South Africans have never heard of AI: What this means for policy*. UCT News, University of Cape Town. https://www.news.uct.ac.za/article/-one-in-three-south-africans-have-never-heard-of-ai-what-this-means-for-policy
22. United Nations Department of Economic and Social Affairs (DESA). (2024). *Addendum on AI and Digital Government. United Nations E-Government Survey 2024*. United Nations. https://desapublications.un.org/sites/default/files/publications/2024-10/Addendum%20on%20AI%20and%20Digital%20Government%20%20E-Government%20Survey%202024.pdf
23. See Treasury Board of Canada Secretariat. (2025, November 28). *Canada launches first register of AI uses in federal government*. https://www.canada.ca/en/treasury-board-secretariat/news/2025/11/canada-launches-first-register-of-ai-uses-in-federal-government.html
24. Commission nationale de l'informatique et des libertés (CNIL).(2026, January 5). *AI system development: CNIL's recommendations to comply with the GDPR*. https://www.cnil.fr/en/ai-system-development-cnils-recommendations-to-comply-gdpr
25. The Prime Minister of Schleswig-Holstein. (2021, November). *Artificial intelligence: Strategic objectives and areas of activity for Schleswig-Holstein*. https://www.schleswig-holstein.de/DE/landesregierung/themen/digitalisierung/kuenstliche-intelligenz/KI_Strategie/_documents/ki__ai_strategy_download.pdf?__blob=publicationFile&v=2
26. See: Act on Activation of AI and Data-Based Administration (January 29, 2026); Framework Act on the Development of Artificial Intelligence and Establishment of Trust, art. 16(4) (as amended January 20, 2026).
27. Cybersecurity and Infrastructure Security Agency. (2024, August 6). *Widespread IT outage due to CrowdStrike update*. https://www.cisa.gov/news-events/alerts/2024/07/19/widespread-it-outage-due-crowdstrike-update
28. Kim, H., & Yang, H. (2025, September 29). *South Korea scrambles to restore digital services after server fire*. Reuters. https://www.reuters.com/world/asia-pacific/south-korea-restores-46-services-after-data-centre-fire-safety-minister-says-2025-09-29/

# Authors



**Catherine Régis** jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n nínú Òfin ní Université de Montréal àti Olùdarí, Social Innovation and International Policy, IVADO. Gẹ́gẹ́ bí onímọ̀ ìjìnlẹ̀ nínú ìṣèjọba AI, ó wà lára àwọn olùdarí ètò ìwádìí ní Canadian AI Safety Institute ní CIFAR, òun ni alága Canada CIFAR nínú AI àti Ẹ̀tọ́ Ọmọnìyàn (Mila), bákan náà ló tún jẹ́ Alága lórí Ìmọ̀ Sáyẹ̀nsì àti Ìṣàkóso Àgbáyé ti AI, Science Diplomacy and Global Governance of AI (Fonds de recherche du Québec).



**Florian Martin-Bariteau** ni alága ikọ̀ olùwádìí nínú ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwùjọ, tó sì tún jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n Onímọ̀ Òfin ní Yunifásítì Ottawa, níbi tí ó ti ń ṣe àkóso ikọ̀ AI + Society Initiative àti Centre for Law, Technology and Society. Òun ni Alágbàṣe Àwọn Olùkọ́ ní Berkman-Klein Center ní Harvard University.

---



**Rachel Adams** ni onkọ̀wé ìwé The New Empire of AI: The Future of Global Inequality. Ó jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n nípa ìṣèwádìí àti Olùdarí Àgbà ní  Leverhulme Centre for the Future of Intelligence ní Yunifásítì Cambridge, àti Olùdásílẹ̀ Àgbà Global Center on AI Governance.




**Peter Parycek** jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n nínú ìmọ̀ ìṣèjọba lórí ayélujára ní ilé ẹ̀kọ́ Yunifásítì Continuing Education Krems. Òun ni olórí ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ìmọ̀ ìṣèjọba lórí ayélujára àti onímọ̀ nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ ní Fraunhofer FOKUS ní Berlin. Wọ́n yàn án sí ìgbìmọ̀ onímọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé ti ìjọba àpapọ̀ ní Germany.



**Brunessen Bertrand** jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n ní ẹ̀ka ìmọ̀ òfin ní Yunifásítì Rennes 1, tó sì gbájúmọ́ ẹ̀ka òfin àti báwọn iléeṣẹ́ ṣe ń ṣàkóso dátà, AI àti ìmọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé. Ìwádìí rẹ̀ dá lórí àwọn ìlànà ìṣiṣẹ́ àjọ ìṣọ̀kan EU, agbára ìjọba àti ààbò lórí ìkànnì ayélujára, tó sì ń bá àwọn ilé iṣẹ́ ìjọba àti àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ kárí ayé ṣiṣẹ́ pọ̀.



**Carlos Affonso Pereira de Souza** jẹ́ onímọ̀ nípa òfin tó ń ṣiṣẹ́ lórí òfin ìgbàlódé, tó sì ń darí ilé iṣẹ́ tó ń rí sí ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwùjọ ní Rio de Janeiro. Ọ̀jọ̀gbọ́n nínú ìmọ̀ òfin àti ìmọ̀ ẹ̀rọ ni, tó sì ti kópa tó lòòrìn sí ìpèsè òfin ààbò àkọ́ọ́lẹ̀ ara ẹni lórí ayélujára ní orílẹ̀ èdè Brazil.



**Jake Okechukwu Effoduh** Olùrànlọ́wọ́ ọ̀jọ̀gbọ́n ní Lincoln Alexander School of Law ní ilé ẹ̀kọ́ Toronto Metropolitan University, tó jẹ́ akọ̀ṣẹ́mọṣẹ́ lórí òfin AI àti ẹ̀tọ́ ọmọnìyàn ní àgbáyé. Ó ti dá sí ọ̀pọ̀ iṣẹ́ lórí  ìdàgbàsókè àwọn ìlànà AI ń gbà ṣiṣẹ́ lọ́pọ̀ orílẹ̀ èdè, tó sì léwájú ọ̀pọ̀ ìwádìí àkànṣe iṣẹ́ lórí Africa àti Canada.



**Hyesun (Melissa) Yoon** jẹ́ Ọ̀jọ̀gbọ́n ní ilé ẹ̀kọ́ Yunifásìtì ìmọ̀ òfin Yunifásítì Hanyang àti Ẹ̀ka ìmọ̀ ẹ̀rọ Artificial Intelligence, AI. Ògbóǹtarìgì ni nínú ìmọ̀ òfin fífi AI ṣàkóso àti ìṣèjọba. Ó ti kópa nínú ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìgbìmọ̀ ìjọba Korea, tó sì ní ìrírí nípa ẹ̀kọ́ káàkiri àgbáyé.

# Ìlànà ìmúlò AI lágbàáyé ní ṣókí

**Àjọ Ìlànà ìmúlò AI lágbàáyé jẹ́ àjọṣepọ̀ iṣẹ́ IVADO, àjọ tó ń ṣe ìwádìí àti ìpèsè ìmọ̀ ní Canada ní ilé ẹ̀kọ́ Université de Montréal, àti AI + Society Initiative ní ilé ẹ̀kọ́ gíga fásitì, University of Ottawa. Ètò náà ní èròńgbà láti pèsè àwọn ìlànà àti ètò tó ṣe é múlò fáwọn tó ń ṣètò káàkiri àgbáyé lórí àwọn ọ̀nà tí wọ́n lè gbà láti kojú ìpèníjà AI tó ń bá gbogbo ayé fínra.**

Léyìn àgbéjáde àkọ́kọ́ lórí ipa tí AI ń ní lórí ìṣèjọba àwaarawa àti ìdúró ire ètò ìdìbò, àjọ náà ṣe àgbéyẹ̀wò ìlànà ìmúlò AI nínú ìṣèjọba. Bí ìṣàmúlò AI ní àwọn ẹ̀ka tó níiṣe pẹ̀lú aráàlú ṣe ń lékún káàkiri àgbáyé, àwọn ìjọba ń dojúkọ àwọn ìpèníjà tó ń pọ̀ sí i nípa ríra nǹkan, ìmúṣe, ìjẹ́rìí, ìṣàkóso ewu, àti díndín ìwà fífì sí apá kan kù. Àbájáde ìpàdé náà kojú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ yìí nípa ṣíṣe àgbékalẹ̀ ìtọ́sọ́nà tó wúlò fún ríra àti gbígbé àwọn ètò AI jáde nínú ìṣàkóso ètò ìṣèjọba lójúnà àti ri dájú pé àwọn ìmọ̀ ẹ̀rọ yìí láti fi ṣe àwọn ohun tí aráàlú ń fẹ́.

Àkọsílẹ̀ ìlànà yìí jẹ́ àgbékalẹ̀ níbi ìpàdé tí Ọ̀jọ̀gbọ́n Catherine Régis àti Florian Martin-Bariteau ṣe agbátẹrù rẹ̀, níbi tí wọ́n ti kó àwọn onímọ̀ ìjínlẹ̀ nípa AI káàkiri àgbáyé jọ. Àjọ Società Italiana per l'Organizzazione Internazionale (SIOI) ní Rome, Italy, ló gbàlejò ìpàdé náà ní oṣù Kejìlá, ọdún 2025. Halima Bachir, Antoine Congost, àti Réjean Roy ti ikọ̀ IVADO's Knowledge Mobilization team wà lára àwọn tó ṣe àtìlẹyìn fún kíkọ iṣẹ́ yìí.

Àkànṣe iṣẹ́ yìí jẹ́ ṣíṣe nípasẹ̀ sí ìdásí CEIMIA, Canada CIFAR Chair lẹ́ka AI and Human Rights ní Mila àti alága ẹ̀ka ìwádìí nípa ìmọ̀ ẹ̀rọ àti àwùjọ ní ilé ẹ̀kọ́ gíga University of Ottawa, àti ìrànlọ́wọ́ ikọ̀ Délégation du Québec à Rome àti SIOI fún ṣíṣe àgbákalẹ̀ ìpàdé náà.

Ìtumọ̀ sí èdè Yorùbá: Toronto Metropolitan University.

## Àwọn tí a lè tọ́ka sí

Catherine Régis, Florian Martin-Bariteau, Rachel Adams, Brunessen Bertrand, Jake Okechukwu Effoduh, Peter Parycek, Carlos Affonso Pereira de Souza & Hyesun Yoon. (2026). *Governing with AI: Building a Transformative and Resilient Public Administration.* The Global Policy Briefs on AI, IVADO / AI + Society Initiative, University of Ottawa. DOI: https://doi.org/10.20381/1npf-nh06

*Àwọn ìwòye tó wà nínú àkọ́ọ́lẹ̀ yìí jẹ́ ti àwọn òǹkọ̀wé kọ̀ọ̀kan.*
*Àwọn irinṣẹ́ AI tí a lò nínú iṣẹ́ yìí ló wà fún ìkẹ́kọ̀ọ́ nìkan tó fi mọ́ àtúnṣe èdè.*

Àjọṣepọ̀ láàárín

IVADO

uOttawa | Initiative IA + Société AI + Society

Pẹ̀lú àtìlẹyìn

CIFAR

ceimia

Iṣẹ́ yìí jẹ́ ṣíṣe látàrí owó tí wọ́n láti ẹ̀ka ìwádìí Canada First Research Excellence Fund.